Anabi - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - jẹ ẹni ti o ṣe pe ti o ba fẹ wọ aaye ẹgbin yio sọ pe: «Allaahummọ inni a‘uudhu biKa minal khubuthi wal khabaaithi

Lati ọdọ Anas - ki Ọlọhun yọnu si i - o sọ pe: Anabi - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - jẹ ẹni ti o ṣe pe ti o ba fẹ wọ aaye ẹgbin yio sọ pe: «Allaahummọ inni a‘uudhu biKa minal khubuthi wal khabaaithi».

[O ni alaafia] [Ohun ti wọn fi ẹnu kò lé lórí ni]

Anabi - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - jẹ ẹni ti o ṣe pe ti o ba fẹ wọ aaye ti yio ti biiya bukaata rẹ, itọ tabi igbẹ, yio wa iṣọra pẹlu Ọlọhun, yio si tun sa di I ki O la a nibi aburo awọn eṣu ni takọ tabi tabo. Wọn si tu al-khubuthi ati al-khabaaith sí aburu ati awọn ẹgbin.

http://www.sunnah.global/hadeeth/yo/show/3150